# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 885 LAGOS SATURDAY SEPT, 7—SEPTEMBER 13 KỌBỌ MEJI (2D) 1963


Awon Ajoji Olopa Wolu :

## Adajo Lambo Yio Da Ejo Oloye Anthony Enahoro Loni

### O ku Osu Meji Ti Nwon Yio Tun Wa Ka

EKO — Ni owurọ oni, ọjọ Abamẹta (Satide) ni a gbọ wipe adajọ Kotu ganran, Ọgbẹni Lambo yio ṣe idajọ Oloye Anthony Enohoro, igbakeji baba ẸGBẸ AFẸNIFẸRE (AG) ti awọn ọlọpa ti mba ṣe ẹjọ lati oṣu melo kan sẹhin wipe o wa ninu awọn ti o ditẹ lati doju Ijọba Apapọ le l'Eko bọlẹ.


Oloye ENAHORO

Awọn ọgá Ọlọpa ti ṣe eto, nwọn si ti ko awọn ọlọpa orişirişi wọlu lati ri wipe awọn janduku enia ko da rogbodiyan silẹ nigbati nwọn ba nka iwe idajọ na ni owurọ yi ni Ọdan.

A tun gbọ wipe nwọn ko ni di awọn ero iworan lọwọ lati wọle lọ gbẹjọ na şugbọn nwọn ko ni jẹki enia rọ wọle pupọ, gbogbo awọn ti nwọn ba si fẹ wọle ni awọn ọlọpa na yio yẹ inu apo ẹwu wọn wo ti o fi de ọdọ awọn (lawyer) agbẹjọro ti o ba wa si kotu loni.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Ijoba Ibadan Fe Gdogun Ti Ogunpa

IBADAN — Irohin ti a gbọ ni alẹ ana lati ọdọ akọwe onirohin wa ni ilu Ibadan ni ti ogun ti awọn alamojuto Ijọba ipinlẹ yi fẹ gbe ti agbara Ogunpa ti o mba wọn ni nkan jẹ lọdọdun lati bi ọdun kẹta sẹhin. Nwọn ni awọn ti şe eto tan lati kọ nkan si ipa odo na ti ko fi ni ya si igbo, ya siju mọ lati ba gbogbo nkan jẹ larin ilu.

Awọn alamojuto Ijọba ibilẹ Ibadan tun şe ikede fun gbogbo awọn ara ilu wipe awọn ko ni fun ẹnikẹni ni iwe aşẹ lati ma kọle si eti Ogunpa mọ. Awọn şọja jagunjagun ti kọ afara pajawiri kan si Odo Ọna dipo eyiti omi gbe lọ ni ọsẹ ti o kọja yi ni Moor Platation.

Gbogbo awọn ẹgbẹ alanu ninu Imale ati Kiriyo ti dide lati ma ke si awọn ọmọ ẹgbẹ wọn wipe ki nwọn şe iranlọwọ owo ati aşọ fun awọn enia ti ikun omi ko wọn lẹru lọ. Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Oke Ọya ti fi iwe ibakẹdun ranşẹ si Olotu Ijọba Iwọ Orun, Oloye Akintọla wipe awọn ba awọn ara Ipinlẹ na kẹdun ọpalaiye ikun omi

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Omi Onijanganjangan Tun Fo Sona Abeokuta

ABẸOKUTA — Gbogbo awọn oni mọto akero ti nwọn gba ọna Abẹokuta ni nwọn bẹrẹsi da pada ni ibikan ti nwọn npe ni Onijanganjangan leti Abẹokuta ni irọlẹ ana nitori omi ti o ti tun fo şoju ọna mọto pẹlu agbara.

Awọn Ọlọpa ni lile ti awọn nle awọn oni mọto yi pada kişe ika rara, nwọn ni ọpọlọpọ awọn mọto miran ninu wọn ni ẹrọ wọn ko lagbara ankọja ninu omi tobẹ, ti nwọn ba si ti de arin omi ti o wọ şoju ọna, nwọn a daku, nitorina ni awọn şe nle wọn pada,

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

### October Meeting 1963.

SATURDAYS 5TH & 26TH OCTOBER. 2ND AND 9TH NOVEMBER. 1963.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P.O. Box 51, Lagos or at the Race Course, Lagos.

Note—No Entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 16th September, 1963.

No Cheque will be accepted.

C. H. E. MILLER
Hon. SECRETARY.


## Iya Ikoko Sa Lo Nile Dokita Patapata

SURULERE—Nwọn ni a ki sore ki a ka sibẹ şugbọn irohin kan ti a gbọ ni alẹ ana nipa Ọdọmọbinrin kan ti o njẹ Comfort Erebor ti Dokita Yinka Olumide gba ẹbi fun tan ti o fi ọmọ ikoko na silẹ, ti o salọ bamubamu ba wa lẹru,

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Omo Egbe Alakuko Da Awon Kan Duro Ninu Egbe

ENUGU—Awon enia pataki meta ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko (N C N C) ti ẹka ipinlẹ Ila Orun ni awọn ẹgbẹ [illegible] ni awon da duro ninu ẹgbẹ fun ọduu marun gbako, ṣugbọn awọn ko yọ wọn patapata. Ẹsun ti nwọn fi nwọn sun ni wipe nwọn njẹ ẹgbẹ na lẹhin ni [illegible].

Oruko awọn ti nwọn da duro ninu ẹgbẹ na ni Ọgbẹni N. O. Udechunwu, akapo fun awọn ọmọ ẹgbẹ, awọn igbimo ti o ṣe iwadi oro rẹ ni o jebi esun ti nwọn fi sun wipe o njẹ ẹgbẹ lẹhin ni ikọkọ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko agbegbe ilu Bende ni Ọgbẹni I. U. Eke paapa jebi irụ ẹsun kanna ti nwọn fi Udechunwu sun. Awọn mẹta ninu ọmọ ẹgbẹ ni nwọn ni ki nwọn ṣe iwadi ọrọ tirẹ.

Ẹnikẹta ni akọwe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko Umuahia ti oruko rẹ njẹ Samu Okwulehi, nwọn da on na duro ṣugbọn nwọn ni awọn ko ti pari iwadi ọrọ tirẹ. Awọn marun ninu awọn ọmọ ẹgbẹ ẹka ti ilu wọn ni nwọn ni ki nwọn ṣe iwadi ọrọ tirẹ.

# Aropileni Kan Jabo Lati Oke

ZURICH —Aropilene akero kan ti awọn Swissair ti o nko ero bọ lati ilu Zurich ni a gbọ wipe o jabọ lati oke, o si kọ'u ile kan ni Duerrnaech gbogbo awọn enia ti o wa ninu rẹ ni nwọn si ku patapata.

Irohin ti a gbọ nipa aropileni na ni wipe ko ju iṣeju marun ti o gbera nilẹ lọ ti o pade agbako yi nitoripe bi o ti gbera nilẹ ni awọn akọwe oniwaya ti o mba ọkọ ofurufu sọrọ ba a sọrọ, lẹhin eyi nwọn ko si gburo rẹ mọ rara.

Nwọn ni enia mejilelogorin ni awọn ero ti o ko, nwọn ni gbogbo awọn ẹbi awọn ti nwọn ku ninu aropileni na ni awọn yio fi iwe tu lọfọ patapata.


CARSON PAINTS AND VANISHES



SOLE AGENTS:

IKORODU TRADING COMPANY
2? & 28, Balogun Street, Lagos,


## E Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe


BE TALLER

Increase your Height.

Details free. Add:—
C. T. Hospital, Azad Market

Delhi 6, India.



LAGOS RACE CLUB

The LAST DAY August Race Meeting will take place on Saturday 7th September, 1963.
First Race at 3 30 p m.
The Hon. Chief Dr. M. A. Majekodunmi will be the Guest of Honour.
Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st. will be paid £2. 10/-, 2nd £1. 10/- and 3rd 10/-.
Also Two Silver Cups will be presented to the best dressed Ladies in national costume and Western dress.

COME ONE COME ALL

Hon. Secretary
Lagos Race Club.

# Awon Olosa Gbo-dekan Ni Iha Osun

ILESHA — Awọn ọga ọlọpa ni Ibadan ni nkan buroku ti oju awọn ri lọdọ awọn ọlọṣa kan ti awọn i fi mọto akẹru ko'ie kakiri agbegbe iha Ọshun ni arin ọsẹ ti o kọja oju awọn ko ri iru rẹ ri. Nwọn ni gbogbo ọsẹ ti o kọja na ni awọn ọlọṣa na fi ko ibọn pẹlu mọto ti awọn fi npiyẹ kiri.

Nwọn ni iwo awọn ọlọṣa na ti awọn yio ko gbọ ni Ẹdẹ, Oshogbo, Ejigbo ati awọn ileto ti o wa lapa awọn ilu nwọnyi ti nwọn bẹrẹsi fi agbara ko wọn nile tibọn tibọn.

Ṣugbọn ti ijẹjọ ya bambari; awọn ọlọpa ni ibikan ni arin Ilesha si Oshogbo ni awọn ṣe alabapade ni Oko Olomoyido ti awọn si fi ija pẹta.

Nwọn ni Eleru sungi loru ọjọ na. Ọga awọn Ọlọṣa na paṣẹ wipe ki awọn ọmọṣẹ rẹ yinbọn si awọn ọlọpa. Ẹniti o subu ẹniti o gbẹgbẹ gba ogbẹ sugbọn ọwọ awọn Ọlọpa tẹ die ninu wọn. Awọn kan tilẹ wa nile iwosan nibiti nwọn gbe ti ntọju wọn lọwọ lọwọ ni ile iwosan awọn Ṣọṣi Ijọ Wesley ni Ilesha.

Awọn ọlọpa tilẹ ri mọto akẹru tuntun ti nwọn fi nko ẹru ti nwọn ji ko kakiri gba lọwọ wọn.

# Alhaji T'oduro F'odaran F'owo Tanran Ni Kotu

KANO—Alhaji Muhamadu ti o nṣe iṣẹ iṣọ'vo ni Feggo, ẹni ọdun mẹtadinlogoji, ti o duro fun ọdaran kan ni iwaju adajọ kotu fi ọgbọn pọnun tanran nibati awọn ọlọpa ni awọn ko ri ọdaran ti o duro fun na.

Awọn ọlọpa ni Marawa ni orukọ ọdaran ti o duro fun na njẹ nwọn ni ẹjọ wipe awọn ka ru ole mọọ lọwọ pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ mẹta ni awọn mba wọn ro lọwọ ki o to di wipe nwọn duro fun un.

Ni ọjọ ti nwọn fẹ bẹrẹsi ro ẹjọ wọn, nwọn pe orukọ Marawa ni Kotu titi, nwọn ko rii, eleyi lo mu ki adajọ paṣẹ wipe ki nwọn lọ wọ Alhaji Muhamadu ti o duro fun wa nibiti o gbe nta ọja rẹ.

Awọn ọlọpa si nwa Marawa ọdaran yi kiri, ṣugbọn Alhaji ti fowo tanran diduro ti o duro fun un niwaju adajọ.

# Oga Olopa Kan Ku Si Ita Ni Enugu

Ọga awọn Ọlọpa kan ti orukọ rẹ njẹ Z.P. Okapkpu ni a gbọ iroh n wipe o ku si ita gbangba ni ọjọ kan ni ilu Enugu laipẹ yi. Ibi ti ijamba iku ti o pa ọga Ọlọpa na ti wa awọn ẹgbẹ rẹ ni awọn ko le sọ.

Nkan ti nwọn le sọ ni alaye fun akọwe iroh in na ti o bi wọn ni wipe ni ojule adugbo kan ti nwọn npe ni Ogui ni awọn aladugbo ti rii ti o npoka iku; nwọn si kesi awọn ọlọpa ẹgbẹ rẹ ki nwọn wa wo nkan ti awọn ri ni adugbo awọn.

Awọn ọlọpa ti o wa sibẹ si ruu lọ si ile awọn lakulaku lati mọ nkan ti o pa;

A gbọ wipe ọdun ti o mbọ yi ni ọga ọlọpa yi ni iati kuro lẹnu iṣẹ nitoripe o ti di ọdun mẹtalelọgbọn ti o ti mba iṣẹ ọlọpa kiri, ti ko ba si ma gba owo oṣọṣu lai ko ṣe iṣẹ mọ fun eyi ti o ti fi sin Ijọba.

# Ha, Kereni Yi Si!



Ṣe iwọ ti ri ki nwọn ṣi kereni kan ri? Bi o ba ri; ri ki o wo aworan Kereni ti nwọn npe ni TOWER BRIDGE ni ilu London yi. O to adọrin odun nisisiyi ti nwọn ti nṣi Kereni na fun gbogbo awọn ọkọ ọkọ nlanla ti o ba nkọja labẹ rẹ. Ọkọ ako agbapo kan ti nwọn npe ni PRETORIA ni o nkọja nibẹ yi.

# ELETI—OFE

(A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 885 SATURDAY SEPT 7 - SEPT 13 1963


## Iwe Si Olotu

### Isele Nla Se Ni Ilu India

KASHMIR— Iṣẹlẹ nla kan ṣẹ ni oru ijẹrin ni ilu India kan ti nwọn npe ni Kaṣimia (Kashmir), ọgọrun enia ni nwọn ku lẹsẹ kanna, awọn ti o farapa nlọ bi rẹrẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


## Jẹki owo rẹ ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamọ Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rẹ fi owo ti o pa si Ile Ipamọ owo. Fi sabẹ abo nitori igbati o ba nfẹ owo lati fi ra ohun ti iwọ o gbin sinu oko, ogun ilẹdu tabi irinṣẹ. Nigbati owo rẹ ba si wà ninu ile ipamọ owo ere a ma ti jẹu ṣẹ jade ni igba de', gbà.



**'Ẹ FI OWO YIN PAMỌ SIBẸ'**

Barclays Bank ti ṣe ọpọlọpọ aworan oni sinima ti a ti mọ dada to si nderin pani, boya ẹ ti ri wọn tẹlẹ. Eyi jamọ itan nipa awọn agbẹ mẹta ti wọn ko eso oko wọn lọsi ọja. - Ẹnikọkan wọn pa owo pupọ.



Ọkan ninu agbẹ nwọnyi si nkọrin lọ tile to nk'igbe ki gbogbo enia le mọ wipe o ti di olowo. Awọn ọrẹ rẹ si nya owo lọwọ rẹ, iyawo rẹ ko ri ohunkohun gbà rara. Agbẹ keji fi owo tirẹ pamo si abẹ ibusun, sugbọn ole kan ji diẹ lọ ninu rẹ ni alẹ, kokoro tun jẹ iyioku.
Agbẹ kẹta logbọn ju wọn lọ.
Gbogbo owo rẹ lo ko lọ tàrata silẹ Ipamọ Owo rẹ Barclays, ki o ba le ra ohun toba fẹ lati gbin sinu oko ni akoko ati irinṣẹ pẹlu.

Ranti wipe, owo rẹ wà labẹ abo ninu Barclays Bank.

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile iṣẹ wọn mbẹ kakiri ni orilẹ ede yi.*

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

## Omi D'orisa N'Ibadan

Tẹlẹtẹlẹ nigbati alaiye ti daiye ni awa Yoruba ti mbọ omi, ṣugbọn nigbati ilaju ti de awọn Kiriyo (Onigbagbọ) ati awọn Imale ko fẹ nani wipe OLORISHA pataki ni omi jẹ fun wọn lati ma bọ afi ọsẹ ti e koja yi ti OMI TUN DI ORISHA KEKERE akunlẹ-bọ ni ilu Ibadan fun ọmọde ati agba.

Minisita ati awọn oṣelu ti o ba wipe awọn ko bọ o nparọ irọ ni. Ko si nnu awọn ti o ṣe mi ju awọn abiyamọ ti o ntọ ọmọ lọwọ lọ. A ko gbọdọ sọ wahala ti awọn alagbafọ ri. Oṣu ṣẹṣẹ pari ni nwọn si ni lati ke awọn aṣọ alaṣọ fun wọn ki nwọn ba tete ri owo oṣu wọn gba.

## Alapata Pade Agbako

Awọn alapata Mọkọla ati Gẹgẹ ri nkan, nwọn ko ri omi fi ṣan ifun ẹran ti nwọn ti pa fun tita. Bi nwọn ti nṣe puta ni nwọn nṣe putu ninu idọti imiẹran ko jẹki abọdi ẹran dun ninu iṣasun ọbẹ alarede si Oke Ado. Omi inu kanga ni baba ẹlẹrọ alọgi nlo ni Ayẹyẹ. Oke Fọkọ, Mọlete ati lọja Gẹgẹ.

Gbogbo aṣọ lo dọti, iyawo tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ gbe ko ro i wẹ. Ṣe ẹnyin na wa ri wipe ọrọ omi kiṣe yẹyẹ rara? Ọpalaiye ti omi yi wa jẹki nniran orin nla kan ti baba mi, ỌMỌ ABATI ATẸFATẸNA ma nko nigba kan bayi: "OMI O, A KO MA ROMI SA O" Oriṣa Yemọja yio gbe mi, Olokun, Ọiọsa oriṣa odo Ọya oriṣa Odo Ọshin ati ti Binue yio kore wa fun emi Ayiluka, emi yio si ma ri omi we, ma si ma ri omi bu mu, nko ni pade agbako iku omi ninu ọdun ti a fẹ bọ si yi! Aṣẹ.

## Ifihan Nkan Ataiyebaiye Wa Nilu Oyinbo

Aworan ọkan ninu awọn ọmọ ilẹ Naijiria ti o nṣe iṣẹ agbẹgilere, Ọgbẹni Ben Osawe ni ẹ nwo yi nibi ti o gbe ti fi ọkan ninu awọn iṣẹ ọna nkan abalaiye ilẹ Naijiria han Alhaji Abdul Maliki, Aṣoju Ijọba Apapọṣe ilẹ Naijiria ti o wa ni London. Oriṣiriṣi igi ere ti nwọn ti gbẹ nigba atijọ ni nwọn ko wa fi han awọn oyinbo nilu wọn.

## A Ye Wa Kale

Mo ro wipe ẹnyin ọrẹ awe mi niran ẹnu foro ti mo ṣe fun yin ni iwọn oṣu keji sẹhin (July) nigbati Ọba awọn Ijẹsha waja wipe nibiti ẹlẹkun nsọkun ni alayọ nyọ. Mo ni Gomina Ọọla Fadahunsi nilu Oyinbo lọdọ Ọba Gẹsi, awọn ijoye Ilesha si nṣe ọfọ Ọwa lọwọ.

Eleyi nikan kọ, mo ni awọn Oyinbo alawo orin ti nwọn npe ni Dẹka (Decca) ni ki Kẹhinde Dairo, ẹru Ọwa ti Ọbabinrin ilu Gẹsi fi Oye M B E da lọla, ni ki o wa ni ilu Oyinbo Ọrọ mi sẹ, o si ti npalẹmọ nisisiyi fun atilọ si ilu Oyinbo na.

## Adura Nla

Lọjọ ti yio ba lọ emi Ayiluka a ṣe aṣeyẹ alamirin fun un, mo si ti sọ fun baba ẹlẹmu ọgọrọ mi ti nwọn npe ni SAMU ỌDẸ ara Esiẹ ti o wa ni OLOPOMẸRIN ni Ebute Mẹtta wipe ki o ba mi wa akeregbe ẹmu ni jaburata, nitoripe awọn ti mo fẹ pe sibi aṣeyẹ na a pọ die.

Awe, ki ẹ mura lati jo ijo asiko nitoripe mo ti sọ fun Ọgbẹni Dairo alara paapa wipe gbogbo awọn ọmọ akọrinta rẹ ni ki o mu lọwọ, ki a le jo orin A YẸ WA KALẸ ti o ṣẹṣẹ kọ daradara.

### MO BA Ẹ YỌ

Mo ba gbogbo ẹnyin ọmọ Ijẹbu-Ode yọ fun ti oye olori awọn Alufa ijọ Ṣọṣi ti nwọn gbe fun ọkan ninu yin Ẹni ọwọ Alufa Kalẹ ti o di Biṣọbu tuntun fun Eko dipo Ologbe Biṣọbu Adelakun Howells. Mo ri mọ Ọgbẹni Kalẹ tipẹ nigbati o ti nṣe iṣẹ tiṣa agba ni opopo Ọdunlami l'Eko. O jẹ ẹnikan ti o fẹran a nsọ otitọ pupọ ju.

Alufa Kalẹ, oye na a mọri o, ỌMỌ ỌBANTA, itọju ilu Eko mọ Ọyọ, Oshogbo, Ogbomọshọ, Abẹokuta Ibadan ati Ijẹbu dọwọ rẹ.

### IYA IJỌ

O dun mi pupọ lati gbọ iku ọkan ninu awọn Olori Akarigbo atijọ, Ọba William Adedoyin, Iya-afin Dorcas Ọ anuga, iya Ijọ Ṣọṣi Methodist Shagamu ti o jalaisi ni mo wi o. Ologbe yi ni o bi Lọya obinrin, Adebisi ("Jamaima") Adebiyi. O dun mi pupọ ti omi Majidun ọna Ikorodu ko ni le jẹki mba wọn lọ sin oku na ni ọla ọjọ ọsẹ (Sunday).



# Iya Kan Binu Ko Omo Re Sile

EKO — Awon olopa ilu Eko mu obinrin abiyamo kan ti o nje Regina Benson a a Aba lo si iwaju kotu awon olopa pelu esun wipe o ju omo re okunrin, omo odun kan abo, si oju titi ti nwon npe ni Broad Street wipe bi o ba le ku ki o ku.

Nigbati akowe kotu ka esun na fun obinrin na, o ni nitoto ni on se be o ni o nidi ti o fi yomo na sonu. Adajo ni on a fe gbo idi abajo na,

Abiyamo yi wa tenu boro, o ni okunrin Ara Abeokuta kan ni on loyun omo na fun. O ni gbogbo igbati on ru oyun omo na kiri, epinni ni o kere ju, okunrin na ko fun on titi on fi bi omo na.

O ni on faa titi oro na ko niru, ehi si npa on. Nipa ti didi lowo omo ti on nru kiri ko je ki on raje se ton, omo na ndi on lowo pupo.

Adajo kotu na bi lere bi okunrin ti o bi omo na ton ba wa laiye o ni o ni o wa, sugbon on ti ri i lupe.

Agbejoro Olopa ti o tako o ni iopeiope okunrin alanu kan ni o gbe omo na kuro loju ona moto nibiti obinrin odaran na gbe e junu si, o si be obinrin yi titi wipe ki o gbe omo re pon sehin sugbon o ko jale. Eleyi ni o mu ki alanu na gbomo na wa si tesan awon olopa.

Adajo pase wipe ki nwon sun oro na siwaju nitoripe on fe ki awon alamojuto eto ojo awon toko-taya se iwadi oro na.

# Afoju Hausa Pomo Kanna Ti O Bi

KANO—Obinrin afoju Hausa kan, Malama Ramatu, iyawo Alufa Ali Rabiu abule Dooa ni Tudun Wada ni agbegbe Kano fi ake pa omo kanna ti o bi lojo ti o nla igi lati fi da'na se obe fun bale re.

Irohin ti a gbo nipa oro na ni wipe Ramotu yi, oju apakan ni o fo, eyiti o ku ti o fi nriran na si wa nse bayibayi, ko si riran febe mo.

Lojo ti o nla igi yi, ko mo wipe omo re narakoro bo wa sibi ti o gbe nfi ake lagi, ni ojiji ni o la ake mo o lori. Awon ti o wa ni itosi odo re gbe omo na digba digba lo sile awon awegbo. Dokita ti nwon ba nibe sa agbara titi lati le gb'omo na la sugbon ko bo sii.

Ramota afoju yi ko bi omo ri, omo kanna ti yio bi niyi.

# Aropileni Alarambara



Awon Gesi oni aropile i tun gbe omiran de o, aropileni ti e nwo aworan re yi le gbera nile ki o fo ni ona ara. Ko ni iwipe o nsare kakiri le ki o to gbera nile fosoke, Awon Oyinbo Gesi ti o nkan aropileni ni nwon igbe e jade nwon si i npe ni BRITAIN'S S.C.I

# Eleti—Ofe D'araba

# Nigerian Wives Get Hints On House-keeping In Britain

LONDON — Five Nigerian wives now living in London have been having hints on shopping, house-keeping and entertaining in Britain during a two-day course held by the Women's Corona Society.

They are Mrs. C Afolabi, wife of the First Secretary at the Nigerian High Commission in London Mrs. N Nwogu from Ndoki, wife of a law student at London University; Mrs. A C O Udo from Onitsha, wife of the Overseas Representative for Nigeria Airways; Mrs. F Godonya from Oturkpo, and Mrs. I k a Aikawa from Kano.

They were guests of the Women's Course Corona Society, a voluntary inter-racial organisation with its headquarters in London, whose membership is open to all women with the object of promoting friendship among the people of the Commonwealth.

The course include talks by speakers with overseas experience, on "Living in Britain" "Party going and giving" and "Are you a good shopper"?

The members of the course also visited Crawley New Town, one of the many towns built near London since the war, to see some of the new housing schemes and the community amenities.

After lunching at the home of the couse secretary of the Society, Mrs Jane Bell, they went on to have tea at an Elizabethan mansion owned by another Society member, Mrs. S Fairbrace, who lived in Nothern Nigeria for a number of years.'

Course members also met the Society President' Lady Robertson, wife of the former Govenor-General of Nigeria and Mrs. J A Macdonald, the Organising Secretary, who lived in Nigeria for twenty five years and helped to establish the Corona school in Lagos.

# Nigerian Books On Show

Edinburgh-Two of the entries in the International Book Exhibition now being held in Edinburgh in conjunction with the Festival, are books written by Nigerians and published by the African Universities Press.

The Exhibition comprises 1,200 books from twenty countries

# Nigerian Police Minister In Britain

LONDON—The Nigerian Minister of State for Police Affairs, the Hon. MAO Olarewaju, who is on twoweek tour of Police Forces and Training Centres in Britain, yesterday, visited Bramashill Police College-Britain's 'University' for Police officers, near Reading in Berkshire. At the College the Minister met Assistant Superintendent O O Edet of the Southern Police Training College, Lagos, who is taking a special training course.

Mr Olarewaju praised the work of the College in training secnior officers from Nigeria. 'The College is producing men who are going to be very useful to us when they return home,' he said. 'Increased ability has already been notice in those who have returned".

The Minister added that he had been highly impressed by the training methods and facilities he had seen at Bramshill. "Our men are made to feel very many more,' he remarked much at home at the College and we hope to send

On Thursday the Minister visited the Detective Training Centre at Wakefield in Yorkshire.

## British Hospital To Open Deep Freeze 'Eye Bank'

LONDON—A deep-freeze "eye bank"—the first of its kind in the world is to be opened shortly at the Queen Victoria Hospital at East Grinstead in Sussex (Southern England).

The corneo- plastic unit at Queen Victoria, set up in 1947, is now the centre of specialised surgery in Britain. Each year up to 150 corneal grafts are carried out on patients from all over the world.

Leading the teams of highly-trained surgeons is Sir Benjamin Rycroft, one of the pioneers of the technique.

Ideally a corneal graft should be performed with a fresh cornea taken from the donor less than twelve hour after death but, as this is difficult to achieve, a regional eye bank was formed at the hospital to preserve corneal material.


**LAGOS RACE CLUB**

**Governor-General's Cup Sweepstake**

Ticket books for the above Sweepstake for Christmas 1963 can now be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course. These Tickets are 2/6d each.

**Pluses, Velvet Velveteen Dam... & Building Materials**

PLEASE COUNSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, Faji Market

LAGOS FIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

## Iscle Nla Se Ni Ilu India

( O bẹrẹ loju ewe kẹrin )

Iṣẹlẹ nla tan titi de gbogbo aroko ilu Kaṣimia na, awọn ti ile wọlu mọlẹ, ti nwọn npọ ka iku le ni ẹdẹgbẹta enia.

A gbọ wipe o to ọdun mejidinlọgbọn nisisiyi ti iru iṣẹlẹ bẹ ti ṣe bẹ ti ṣe ni ilu India, sugbọn ko le to eleyi rara.

---

## Omi Onijanganjangan Tun Fo Sona Abeokuta

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

A gbọ irohin wipe ikun omi yi ti nṣe ẹru jẹjẹ fun ọpọlọpọ awọn agbalagba ni ilu Abẹokuta ati Ibadan. Awọn kan ni ẹṣẹ ọwọ wa ni o pọju ti o dabi ẹni wipe Ọlọrun fẹ binu si wa. Nwọn ni ọpọlọpọ wa ni a ngbe ẹjọ elẹbi fun alare, ika wa si ti pọju ni arin ilu. O yẹ ki a ma gbadura nigba gbogbo.

## Ijoba Ibadan Fe Gbogun Ti Ogunpa

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

ti o ṣe wọn lofọ.

Awọn alamojuto Ijọba Ipinlẹ Ariwa na si fi ọgọrun taun (tons) irẹsi ransẹ si awọn ti jamba omi na sọ di ẹdun-arinlẹ wipe ki Ijọba pin in fun wọn. Awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe l'Eko tun ṣe ileri owo gọbọyi kan lati fi ran awọn ti omi wo ile wọn lọwọ.

Ninu awọn Ijọba ajoji ti a gbọ wipe nwọn tun fi ẹbun iranlọwọ ranṣẹ si awọn ti omi pa ladanu ni Ijọba awọn Israeli, ọdunrun (300) ẹru aṣọ awọtẹlẹ ni nwọn fi ranṣẹ si wọn fun iranlọwọ.

## Iya Ikoko SaLo Nile Dokita Patapata

( O bẹrẹ loju ewe kinni )

Irohin ti a gbọ nipa ọrọ na ni wipe awọn abanu kan ni nwọn ri Obinrin aboyun na nibi ti o gbe nrọbi ni ojude gbangbo ti nwọn si ṣe ajo rẹ, ti nwọn run wa si ile igbẹbi Dokita Olumide na ni ọjọ Jimọ ti o kọja,

Obinrin na si biọmọ na tibi, tire, o ni namber 19A, ni opopo Ajẹlẹ l'Eko ni on ngbe pẹlu ọkọ on; nigbati o di owurọ ọjọ keji nwọn ko ba lẹgbẹ ọmọ rẹ ti o tẹ silẹ, o ti sa lọ. Ere ni awada ni; nigbati awọn nọọsi ti o ntọju rẹ pẹlu ikoko ọmọ ti o ṣẹṣẹ bi na reti rẹ titi ti nwọn ko ri nwọn wa a lọ si ile ti o ni on ngbe l'Eko.

Awọn ara ile ti o juwe ni opopo Ajẹlẹ ni awọn ko mọọ rara. Dokita Olumide ko ọrọ na lọ si ọdọ awọn ọlọpa, nwọn si baa wa Obinrin iya ikoko na titi, nwọn ko ti rii.

Ni ana ọjọ Jimọ ni ọmọ na di ọjọ mẹjọ ti nwọn bii nwọn si ko o jade ni ana, nwọn sọ ọmọ na ni orukọ ninu ile dokita ti iya ikoko na kọ ọmọ rẹ si. Nwọn ntọju ọmọ na lọwọ daradara nile abiyamọ ti iya na bii si.

---

## HU—HA—HA

HU—HA—HA

## E Surukuru! Eyo Adamorisha

EKO—Irohin ta si wa leti fẹrẹ wipe awọn ẹlẹyo ti nṣe orisirisi ipade larin ẹgbẹ kọkan ti nṣe ẹyọ l'Eko, awọn bi ẹyọ Adimu, Agere, Oniko, Ọlọgẹdẹ, Bajulaiye, Onifilapupa, Ọọja, Ashogbon, Olorogun, Oluwa, Modilẹ, Onitẹlọ, ati awọn miran, lati ṣe ẹyọ fuu Ijọba Republic ti awọn ara Nigeria'fẹ gba ni oṣu ti mbọ.

A gbọ wipe Adajọ agba Kotu Eko kan, Oloye G B A Coker ni yio sanwo ẹsunmẹrẹ itẹfada ere ẹyọ na lati fi sin oku Olobe baba rẹ. Ọjọ gan ti nwọn yio ṣe ẹyọ na ni nwọn ko ti sọ fun wa,

## O ku Osu Meji Ti Nwon Yio Tun Wa Ka

(o bẹrẹ loju ewe kinni)

Ọlọla Tafawa Balewa, Olotu Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria ṣe ikede ipade ti o ba gbogbo awọn Olotu Ipinlẹ mẹrin yoku ṣe ni Eko lọsan ana wipe awọn akọwe on ti pari eto lati tun gbogbo ara ilu Nigeria ka ni oṣu meji loni; iyẹn ni wipe nwọn yio tun wa ka ninu oṣu kọkanla ọdun yi (November).

Gẹgẹbi ikede ti o jade nipa gbogbo enia ti nwọn yio ka tọmọtọmọ na, ni ọjọ Iṣẹgun (Tuesday) ọjọ karun oṣu kọkanla (Noverber) ọdun titi di ọjọ Ẹti (Jimọ) ọjọ kẹjọ oṣu na. O jẹ ọjọ mẹta gbako ni nwọn yio fi ka gbogbo enia ilu yi jake jado.

Nwọn ni enia kika ko ni wipe enia ko si nile rara, ẹniti awọn ba ri ni awọn yio ka. Nwọn ni awọn si ti ṣe eto lati da awọn akọwe akanṣe ipinlẹ kan pọ mọ ikeji, ki [illegible] mọ le ri aye ṣe eru [illegible].

Ninu awọn Olotu Ijọba ti o wa nibi ipade aṣiri na lana ni Oloye S. L. Akintọla lati Ibadan; Dokita Okpara lati Enugu, Ọlọla Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto lati Kaduna ati Oloye Denis Osadebay lati Benin City.



Oloye S L AKINTỌLA



Oba Adeniji Adele II

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos
Phone 23370; Editor: (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15,Kosọkọ Street, Lagos, Box 457